Chief Secretary to the Govt.


# EKO AKETE.

"Emi yio fi ohun ti o ndun Makunnu han awon Alagbara, Ngo si je Alagbawi awon Odi."—W. T. Stead.

Vol. III. No, 107. SATURDAY, AUG. 2, 1924. Fourpence.



## DURO THOMAS.

55, MASSEY STREET, LAGOS, (NIGERIA.)

P.O. Box 374. Telephone No. 243.

*The Best House for every Description of German Goods.*

"**Specialities: Enamelware Beer, Wine, Iron Bedsteads, Ruby Plates, Rubber Beads of all kinds, Clay and Briar Pipes, Champagne, Cement, Biscuits in cases, Gun Powder, Wire Nails Raugoon and original Ballam Rice, Accordeons, Piano, Padlocks, Beads, etc., etc., etc.**"

---

CHIEF SECRETARY'S OFFICE 5 AUG. 1924 LAGOS

## N. V. HANDLEMATTSCHAPPIJ V.H.

OYINBO **J. F. SICK**

Ọba Ilẹkẹ, Ile Ilẹkẹ, 9, Ita 'Bode lailai, Eko.

A jẹ Ajirera ninu òwò Ilẹkẹ, oriṣiriṣi Ilẹkẹ wọnyi wa ni tita:—

Ilẹkẹ Oyinbo, Ilẹkẹ Rubber, Ilẹkẹ Olomi Waji, Ilẹkẹ Onikẹkẹ, Ilẹkẹ Elejo, Ilẹkẹ Ayinrin, Ilẹkẹ Oniwõrò ati Fadaka, Ilẹkẹ Kerewu, Ilẹkẹ Jòjò, Ilẹkẹ Òlokuta, Ilẹkẹ Oloruka, Ilẹkẹ Ẹleranko, Ilẹkẹ didan Yinrinyinrin, Ilẹkẹ Meremere, Ilẹkẹ Mọjọkun, Ilẹkẹ Adumadan.

Ẹ wa wo Ile ọja wa; A ni nkan wọnyi fun tita:—

Ikoko taba Onigi, Jigi, Aṣọ Aran, Ẹrọ agbado, Ife, Ọti Elewuro (*Beer*) ati Eleso Àjàrà (*Wine*), Awọn onjẹ ipanu, aṣọ iṣ'ọṣọ, Ẹrọ ere ọmọde, Ohun Ọṣọ, Abẹlà (*Candles*) ati ẹgbagbeje ọja miran.

A nta Maşini *Vesta*, a si ni *Cement* atata ti Portland ati irin pipọn abẹ oni *Diamond*. Idi òwò wa wa ni Rotterdam, a si ni Ile owo ni:—Calabar, Gablonz (Czecko-Slovakia) Gold Coast, Accra, Lome Hamburg, London, Venice (Italy).

# John Walkden & Co. Ltd.

SUNDRIES DEPT.

MARINA, LAGOS.

## We recommend you to try our :—

"ELEPHANT" BEER
GINGER ALE
LEMONADE
RED BUFFALO GIN
BLACK PRINCE GIN
GILBEYS GIN
OLD TOM GIN

***QUALITY THE BEST.***

ALL PRICES REDUCED.

*We hold a large stock of various Sundry Goods at cheap prices.*

---

# CONGOLEUM SQUARES.

## THE LATEST IN FLOOR COVERINGS.

We have been appointed Sole Agents for Nigeria for CONGOLEUM SQUARES, and can horoughly recommend them on account of their splendid wearing qualities, and also because of the cheapness in price. They are especially suitable for cement floors.

They are easy to keep clean, but hard to wear out, unaffected by dampness, moisture, insects, rot-proof, and strictly sanitary.

We hold a stock in a good range of patterns, and various sizes from 6 feet by 6 feet, to 15 feet by 9 feet.

*We invite you to come and inspect same at :—*

JOHN WALKDEN & CO. LTD.,
MARINA, LAGOS.

*Editor* :—
ADEOYE DENIGA,
*Offices*: 22 & 24, Williams Street,
P.O. Box 286,
Lagos, Nigeria.

ASAN-SILĘ NI OWO GBIGBA RĘ.

| Eko. | | Ilu miran ni Nigeria. | Ilu Okere. |
|---|---|---|---|
| Ọdun kan | 12/- | 13/- | 14/- |
| Oṣu mẹfa | 6/- | 6/6d. | 7/- |
| Oṣu mẹta | 3/- | 3/6d. | 4/- |

Ę fi owo ati *Letter* ranṣẹ si *Editor*.

## GBOHUN-GBOHUN.

———:o:———

OWO O, IWORO OWO!

O ta si wa leti fẹnrẹn pe ọwọ awọn Ẹgbẹ Ogun Igbala ti ilẹ yi (*Salvation Army*) tẹ ohun ti nwọn ti nwa lati ọjọ gbọrọ sẹhin: eyini ni Ilẹ ti nwọn yio kọ Ile Isin tiwọn si; ni koipẹ yi ni a sọ pe awọn Olori Ẹgbẹ nā na Ọgbẹni S. J. Palmer ti Sapẹlẹ ni kunmọ Ẹgbẹdogun Pọun (£3,000) fun rira ti nwọn ra ilẹ gbẹrẹfu Ọgbẹni na ti o wa ni Ita Kakawa ti o kọju si ile Ọgbẹni J. W. Vaughan (Olōgbe) ti o si kọ iha si Ile ọmọ "Odubulẹta" eyini ni Ọgbẹni Candido da Rocha arowolo. Aba awọn Ẹgbẹ yi yọ fun orire wọn na papa fun akoko yi ti o jẹ pe ipa ni enia fi le ri ilẹ ti o bọ si gbangba bayi ra fun Ile Isin ti yio wa ni ọjutaiye ni igboro ilẹ yi; ko ni pe a ṣẹṣẹ nrin lọ jinna rere bi ọna Mẹkunọn. Ọgbẹni Palmer na si tun ku orire owo to tun ṣubu si yi.

ẸṢE? Ẹ BA WA GBE ORIN WAKA YI; KAI!!!

MARABA, MARABA, Ẹ MA W'OLẸ.

A ki Ọgbẹni Ọlọla E. H. Oke ti Ibadan kabọ; Ọgbẹni Ọlọla na de sibi ni *Monday* ọsẹ yi lati wa si Ajọ Igbimọ Aṣofin ti *Nigeria* ninu eyiti a ṣẹṣẹ yan a si ni lọlọyi bi Aṣofin Igberiko Ọyọ; a fi Ọlọla na "jiyọ" ninu Ajọ Igbimọ Aṣofin na ti a ṣe ni *Tuesday* ọsẹ yi

Bi o tilẹ jẹ pe Ọgbẹni Ọlọla yi to ẹni ọgọrin ọdun, sibẹ wiwo rẹ ko ju ẹni ọgọta ọdun lọ loju wa. Ninu eyiti o wọ ilẹ yi, a o ma wo bi awọn agbajọpọ Ijọ Ọmọ Ibilẹ (*African Communion*) ti o wa larin wa nibi yio jafara ati ṣe bẹbẹ fun u bi o ti tọ; kosi ẹniti ko mọ pe opo kan fau-fau ni Ọgbẹni yi jẹ ni *Church* Ọmọ Ibilẹ, iba ṣe nibi tabi ni Ibadan. A ko le ṣẹṣẹ nawọ k'a to f orun han.

EREDI ẸṢẸ GIRIGIRI LỌNA ỌRUN YI? ẸNITI KO MA JẸ GBI KO MA NKU GBI!!!

Lemọlemọ ti enia nku lojiji lode nisinsinyi ṣe nkọ ẹnikẹni l'omi'nu, otutu Ọwọrẹ ti o nja nisinsinyi ki nṣe atẹgun to nfẹ gbà-gbà gbà-gbà, gẹgẹ bi a tile ṣakiyesi rẹ; wẹrẹ-wọrẹ ti otutu na nfẹ si nwọ enia lara de egungun, tobẹ ti a fi gbọ pe ki wiwẹ omi tutu dinku. Emi la mọ eyi si o? Ki sa nṣe pe a tun bọ si ọdun Ayọkẹlẹ bi ti idunfa l'ẹkeji ni? Ki Baba maṣai fi ṣiṣọ Rẹ ṣọ ni ninu Aluba yi.

ỌRAN GBOGBO LORI ṢILE.

A gbọ pe awọn Ijọ C.M.S. ra arakuyamu Ile Ologbe Ọlọla Dr. O. Johnson ti Opopo nla ti a npe ni Gbọngan Okuta Iyebiye (*Marble Hall*) ni Ẹgbẹdogun Pọun (£3000) ati pe a fẹ fi kọ Ile Iwe giga ti awọn Obinrin ti yio jẹ ẹka Ile Iwe giga ti ọna Ebute Ṣọṣi Alagogo; a sọ pe awọn Ẹgbẹ Ogun Igbala lo ti fẹ ra ibẹ ri ni Ẹgbẹdọgbọn Pọun (£5000) ṣugbọn o dabi ẹnipe awọn Olotu Ile na ti a ro pe nwọn jẹ *Member* C.M.S. ko fẹ ki Ile na bọ si ọwọ ẹlomiran ni; bi eyi ba ri bẹ njẹ ōtọ ni owe wa yi to wipe:—Ara ẹni la kọ bọ k'a to bọ Agbọnniregun, t'ara ẹni l'a ko l'esu.

## ẸNI T'O SỌ'KO, LO NRETI OGULUTU.

Ni ọsẹ bi meji sẹhin ti a ri Wosika ojut'aiye ti Iya Afin C. Ọlajumọkẹ Ọbasa kọ sinu Iwe-irohin *African Messenger* si Ọgbẹni A. E. Norman Williams bi iriju Alufa Ijọ Onidunkun Oyinbo (*St. Paul's Breadfruit Church*) mu ni sọ sinu pe koba'kungbe ọrọ ti Iya Afin yi sọ ṣàkàṣàkà si Ọgbẹni ti o kọ iwe na si lara, ko ni bi ọmọ to rọ; tọ̀tọ-tọ̀tọ nigbati a si ka esi iwe yi ti Ọgbẹni Williams kọ sinu Iwe-irohin kanna yi ti ọsẹ to kọja, adura ti a gba lọkan wa ni pe ki a maṣe tẹ lọwọ ẹniti o fẹran wa, tabi ti o nbọwọ ipo ti a wa fun wa; esi na mu ki kẹkẹ p'ohun m'awoko lẹnu; lalai ni tanma lati da si ọrọ yi ti o ti di iyọrọ ti o si ti bo awọn "ṣọbọṣọla" miran bi igbati ekuru bo aja, a ni ireti pe *Sissy* papa yio ti mọ aṣiṣe ti o ṣe loju wa nipa didasi ọrọ ọkọnrin meji, ti a si ro pe iba yẹ ẹ bioṣepe o ṣe ẹnu mẹnrẹn ni tabi ki o mọ bi on ti ma fi ẹsọ da si i, ti ko ni ni ti a nfori jona gborun ara ẹni binu.

Ẹwẹ̀, a si tun ri ka pe Iya Afin na sọ pe iyekan ni t'on ti Ọgbẹni na jẹ, bi eyi ba ri bẹ; njẹ ọgbọn ha wa ninu pe ki a tu iyekan ẹni l'aṣọ ni ihoho ni opopo-ode bi Ọja Ita Faji—ọrọ lo lọ bẹ o—ki iyekan ẹni na ti a hu ni iwa iwọsi ni gbangba bayi si gbe ẹnu rẹ fun alagbafọ, lalai le ta putu rara? Nitotọ eku to da eyi silẹ lo njẹ ẹda, a si ro pe eyi ni yio jẹ opin fifi oju tinrin enia: bi o fi oju ana wo'ku ẹbọra a bọ l'aṣọ. Agbalagba ki nṣe langba-langba.

## ỌNA ỌFUN, ỌNA ỌRUN, GASIKIYA NI!

Bi ọrọ yi ti jẹ otitọ to, o farahan gbangba ni *Tuesday* ọsẹ yi nigbati ọkọnrin kan ti o ṣẹṣẹ ṣiwọ lẹnu iṣẹ l'ọjọ na gan si d'ero ọrun lojiji, bi o ti njẹ iresi ti o da nibi Mọṣalaṣi kan l'apa isọ awọn Ẹleja ni Ọja Ereko. A gbọ pe arun ti o wọ'lu lati Oko Awo wa lo kọlu u ti o si fi di oku bi idan bẹ; wara-were awọn Ọpa Ọba ti ṣi gan-ngan de'bẹ nwọn si gbe oku rẹ lọ. A gbọ pe awọn Ọpa Ọba na ra obinrin ti ọkọnrin yi da iresi jẹ lọwọ rẹ mu, sagbọn laiṣiyemeji, a ro pe nwọn yio ti fi silẹ nisinsinyi; nitori ȯwȯ iresi sise-ta ni a sọ pe obinrin na nṣe. Aluba lo de, iṣu jona, ẹjẹ ko kan t'ọbẹ.

## BARUWA NDAJI, O DI GBERE!!!

Bi Ọgbẹni Lawani Baruwa ti Ita Ọbadina ti nlọ ki ọrẹ rẹ kan ti o fẹ si diẹ lati Okepopo lọsẹ yi, bẹni a sọ pe nkankan kọlu u ti o fi mu apa kan ati ẹsẹ rẹ kan rọ, o si ṣubu lulẹ; bi iṣẹju, awọn "ẹru" Ọlọrun ti o wa nibẹ si gbe sinu ile kan, ãjo si npe ãjo ranṣẹ; ṣugbọn anu ṣe ni pe Ọgbẹni na ku si'le ti a gbe e wọ na ñi *Monday* ọsẹ yi, a si sin i lẹhinna.

A sọ pe ko ju iwọn ọjọ melo kan sẹhin ti o ngba awọn Janma ti o wa ni Mọṣalaṣi adugbo rẹ ni'yanju niti owo dida fun ṣiṣe iṣẹ Mọṣalaṣi na to ku; ki a si gbọ pe irufẹ ẹni bẹ d'ero ọrun laito ọsẹ kan lẹhin eyi, ko ha mu ẹnuẹni kọ jẹjẹ bi? Nitotọ iku mbẹ; alimutu ki Baba maṣai foriji i.

A ba awọn ọmọ rẹ ati awọn ẹgbẹ ati Ọgba rẹ daro Ọfọ yi. Ẹku Ajalu.

## ỌMỌ ỌDUN MẸTA KO ṢE GBE JO.

Ninu oṣu tokọja ni Iwe Irohin wa "*Eko Akete*" nlọ si ọmọ ọdun mẹta; A dupẹ lọwọ awọn ọrẹ wa ti nwọn nkọ iwe sinu rẹ, papa Atari Ajanaku ẹniti gege rẹ ki ṣai ji ẹnikẹni pẹpẹ ni igboro ilẹ yi, tabi jake-jado gbogbo aiye, lati igbati o ti bẹrẹ iwe kikọ rẹ fun wa. Ọwọ gbogbo wa a r'oke karikari o, fun t'anfani—Aṣẹ.

## AGBO MEJI KO LE MU'MI L'AKOTO! BẸ L'AIYE RI, A! AIYE AKAMARA!!!

Anu ṣe ni lati gbọ pe awọn olotu Ijọ nla kan da Oye Alufa kan to wa l'abẹ wọn duro fun Wasi kan ti a ni o ṣe ni Ṣọṣi ibiti a gbe ñi ko ma ṣe iranlọwọ fun Alufa Agba to wa nibẹ; a sọ pe ọrọ imugun ti a ni o sọ.

lori igi ibiti o gbe wasu na run awọn olotu Ijọ na ninu tobẹ ti a fi wipe a da oye Alufa kikun ti iba jẹ lọduni duro fun ọdun kan gbako; eyiti o tun ṣo ni lọwọ ninu ọrọ ...a nipe a sọ pe a gba *Sunday* lọwọ Alufa ...kere na, a si gbe *Satide* le e lọwọ, eyini ...pe a gba ọmọ pupa ṣ'ẹgbẹ rodorodo kan ...ṣẹṣẹ nfẹ lọwọ rẹ; ki Ọlọrun ma ṣai ...dun alagbara ni suru!!!

EBUTE AWO D'EBUTE AGẸMỌ,

BABA ṢỌ NI!!!

Babaruru ti Ijọba sọ ççgba panu yika gbogbo ibiti arun ajinipa to sọ'lẹ l'Ebute Awo lẹnu ọjọ melo to kọja yi, fihan gbangba pe arun to bẹ sibẹ na kuro ni ohun ti ẹnikẹni le fi ọwọ yẹpẹrẹ mu; a se ...upọ ninu awọn to ngbe adugbo na mọ, a si nṣe itọju wọn, ki arun na maṣe tun le ri aye fo fẹrẹ sọda lọ sibomiran. Ijọba si ti yọda Ẹgbẹrun pọun (£1000) ṣandi ninu owo Ilu lati lo fun iṣẹ ti awọn Dokita Ọba nṣe nibẹ. Lati ki arun na wọ.

K'ỌLỌRUN JẸ KI ẸMI RI ẸMI.

A ki awọn ẹbi ati iyekan iya afin Sabitiu Alakẹ, Ape to pe, ọmọluwabi ẹlẹyinju ẹgẹ, ku ilede gbajumọ ọmọ wọn obinrin yi to lọ si Abẹokuta ni Alamisi ọsẹ to kọja lati lọ ki Sinọbu Anikẹ ẹgbọn rẹ nibẹ. Sabitiu jẹ ọkan ninu awọn obinrin pataki to nka Iwe-irohin wa lọsọsẹ ni aka gbadun lati igbati a ti bẹrẹ, ko si ṣeṣi jẹ wa ni kọbọ kan ri.

---

## Thanks for Sympathy.

Mr. R. O. Staveley begs to return sincere and grateful thanks to all kind friends, here and abroad, who have sympathised with him by personal calls, letters and telegrams for the irreparable loss sustained by the death of his beloved wife which occured at 44, Campbell Street on Sunday the 28th July, 1924.

---

OJOJO NṢE OGUN ARA OGUN KO LE.

A gbọ pe o fẹ si Ọlọla Kitoyi Ajasa diẹ, Ọlọrun ko mu alafia wa.

ORU L'ỌRỌ NRIN.

Aisan pọ l'ode nisisiyi, nitorina a bẹ gbogbo ẹnyin to nwọ'de oru, ẹ so agbejẹ mọ'di, oru l'ọrọ nrin.

---

## This, That, and the Other

*By an old Crow.*

### Strange Advertisement.

As if the case of one Mr. Arthur Drew Clifton alias Professor Zazra who was fined £25 in Bow Street Police Court last year was not enough to serve as a caution, the following advertisement appeared in *John Bull* for 12/7/24:—"Good Luck follows Ju-Ju, the Nigerian Mascot. Don't merely hope for better Luck—make it a certainty by wearing a fascinating Ju-Ju Charm. Everything you touch will turn out well"...etc etc.

Among the testimonials published is one which says "Everything I have touched prospered." But one would rather have liked to see a list of the true names of proprietors of this strange business—how far they have themselves *prospered* and then!!!

### Islam and Sectarianism.

A controversy on this subject is now going on in the *Nigerian Spectator* being originated from the *African Messenger*. Says one: "Sectarianism, a substitute in English language of the *original* word in Arabic."

"What original word in Arabic?" Asks the other.

Meanwhile, this *mysterious* Arabic word lies peaceably in the brain of one of them. Let us ask Mohd. B. B. S. if the word can be brought out!!! and being brought out if it can help him out of the muddle.

### Latest Discovery.

Says *The Daily Gleaner* (18/6/24):—

"White Indians have been found in Darien...a new and curious people have come to light in a country but a few hundred miles from Jamaica, a country which has been in touch with civilisation for some four hundred years, though parts of it still remain to be adequately explored.........men and women with blue eyes and golden hair—not albinos....."

Well done! In face of the above we need not speak too strongly to ethnologists, or, is it safer to call them archaeologists? They should wake up and sieze the opportunities which they yet have inspite of the fact that civilisation is world-wide.

In this part of the world, *Sabarumas*, we think, are the plentiest and, it will not surprice us if in these days our Forestry Department discovers a new tribe of *White Sabarumas* in far remote and cold regions of the Northern Province!

### "The Advanced Opinion."

The first issue of this paper came out on Wednesday this week. We congratulate its Editor Mr. Ellis Nicol St. John and wish the paper a long life of usefulness in the community.

It is imposible to say definitely at present whether or not the paper will remain bilingual as evidenced in its first issue which contains Spanish and English. Yoruba is another popular language in Lagos and if added *The Advanced Opinion* will be trilingual!!!

AN OLD CROW.

**EKO AKETE.**

EKO, SATURDAY, AUGUST 2, 1924.

## BAYI LÃ ṢE NI'LU ẸNI, ÈWỌ IBOMIRAN.

Ko si ilu kan bi o ti wu ki o kere tabi ki o tobi to, ti ko ni ni awọn ohun wõnni ti yio ma jẹ abo rẹ; ni igba lailai titi di nkan bi ọdun melo sẹhin, ilu Eko tutu bi ọdúnd n fun ẹnikẹni tobẹ ti ko si ẹniti yio wọ inu rẹ ti ko ni ṣe gbẹdẹ fun, bi o ti wu, ki oluwarẹ ki o jẹ ẹdun arinlẹ to, tabi ki o ma ni ọkan lọwọ bi aja; irufẹ irọra ti t'onile t'alejo nri nigbana ni erekuṣu yi ti o fi mu ki diẹ ninu awọn ajeji ti ara rọ bayi gbagbera lati ma ṣubi ṣupa nipa biberẹsi huwa ẹgbin lo mu owe yi wa :—

Eko gb'ole, o gb'ọlẹ,
O gba—( ki o ma ye ọ )

Ni akoko ti a nwi yi, ṣaṣa ni ẹniti ko le jẹun larin awo tabi ti ko le "dabira" nipa pe ki oluwarẹ wọ'le jade fun ohunkohun ti o ba kan ni ṣiṣe; ṣugbọn lẹnu ọdun diẹ sẹhin yi nkọ? Kilari? Ko ha di ki ati jẹun ni ọpọlọpọ ẹlomiran lara bi? Ti ọwọ ko b'ọwọ, ti ẹsẹ ko si b'ẹsẹ fun awọn ẹlomiran mọ?

A ko ha ri ọgọrọ enia ni sanmani isinsinyi ti nwọn nji lalai le ba ẹgbã ji, ti gbogbo rẹ di ọkakara to wọ'le okokoro; ọja to wa ni sabu ẹlomiran ti oluwarẹ nmọ loju nipa aita ọja na ni ko to ro ni, tabi ti airi'ṣẹ ṣe to ti mu ọpọlọpọ awọn miran di aya'ju le-jẹun-mọ-'bi-ọbẹ-dun; owo-ile sisan ti ẹlomiran ko ri san tabi ti o ṣẹ si irufẹ ẹnitẹ l'ọrun ni ko di ipaya fun oluwarẹ ni, tabi ti aileri tọrọ (3d) tabi sisi (6d) gbe ju silẹ fun Ereko tabi Ita Faji l'ararọ, eyiti ima mu ija ati asọ wá larin okọlaya ninu ile. Adiro awọn ẹlomiran ko ha ti nṣofọ nisinsinyi bi? Bẹni, ebi ko sa mọ pe okan ko si ni le.

Irufẹ ọda yi lo da lo mu Biṣi Akewi wa kọrin nigbakan pe:—

Ibanujẹ ṣile,
Ohun t'owo nṣe ni'lẹ yi ko ṣẹ
Ibanujẹ ṣile,
Ohun t'owo nṣe ni'lẹ yi ko ṣẹ
Gbogbo enia lo d' oku
Lo d' oku o, oku alai re'tẹ
Gbogbo enia lo d' oku
Lo d' oku o, oku alai re'tẹ
Ab'ẹgbọ, Ibanujẹ ṣile
Ohun t'owo nṣe ni'lẹ yi ko ṣẹ.

Ṣugbọn ninu gbogbo ọrọ ti a nsọ yi, kini a ri to nibẹ? Nigbati oriṣiriṣ ẽwọ ilu nwọ 'lu, ti àṣà gbogbo ti a ko gbọdọ da ni 'lu ndi dida, ti iṣasun ọbẹ ndi gbigbe ru kiri opopo ode, ti iṣu tútù ndi ohun ṣiṣi mọ'ri ta kakiri igboro, ti Igbin di asure si polowo jake-jado ilẹ yi, ti Imi Ẹlẹbọtọ di ohun ti a nyọ ṣẹṣẹ si fun gbigberu kiri ta lati adugbo kan de ekeji ati ẹgbagbeje ewo miran ti o di arigbọdọ wi ikun ni'mu egbere; ogo ni o dabi ẹnipe owo nsa kuro ni ilu wọ igbo lọ, ti inira npe inira ranṣẹ, ti gbogbo nkan si di tipẹ-ti-ẹ'ẹ. Boya eyiti a sọ yi le pa awọn alaironu miran lẹrin, pe ewo ni *Editor "Eko Akete"* tun fọ jolẹ y wẹ, bi a ba ri irufẹ ẹnibẹ a fẹ ki o mọ pe k si ilu kan libẹ ọrun ti ko ni ipọri tirẹ nip mimọ etutu iṣẹdalẹ rẹ; ẹnikẹni ti o ba nsaba nwọ ọkọ-Oyinbo nlanla (*mail boat*) yio ripe kété ti ọkọ na ba ti de ibi ti a mọ bi oju ija, ni iwọ yio gbọ fifọ igo ọti olowo iyebiye kan ti ọgakọ na yio fọ s'ara ọkọ na, ti igo ọti na yio si ṣe "tábú' sinu omi okun, ( Awa papa fi oju wa gãnni eyi ni idunrin ọhun ) Njẹ ọmọ-iya, iwọ mọ itumọ eyi baun? Bi ko ba nidi, obinrin ma njẹ Kumolu? Ẹ fi lakaye gbe e, nitori onilakaye l'ọrọ mba wi.

Loju wa ohun inira ti o de ode isinsiny kuro ni fifi ọwọ lu ọwọ si, oyẹ ki awọn Ẹgb Maiyegun kan si o'ori wa ni Iga Idunganran; o si yẹ ki awọn Oloye Onilila funfun san ṣokoto giri; Eletu Odibo, Olorogun, Oluwa, Aborẹ-Ọba, Ẹ ko ngbohun wa na?

Etutu, Etutu, Etutu, ni ode gba lakoko vi, ati kike l ba Ijọba wa fun iranlọwọ lati sofin ewọ ti awọn enia nṣe gẹgẹ bi a ti lã silẹ bayi.

Ki Kiriyo mura adura gbigba kikan kikan, ki Musulumi si ma fa Tęsuba rę lęmolęmo fun idaduro ohun to mbę l'ode nisisinyi. Ilu ki nsa kere k'o ma ni Atan. Aşę wa niwaju o!!!

## Ę KU ATIJO!

[*Lati owo* ATARI AJANAKU.]

Si Oni'we-irohin "EKO AKETE."

Mo bęrę f'oji.

Irufę kiki bayi ni a nki ęniti o ba ti to ojo męta tabi ju bę lo ti a ti ri, tabi ti a ti gburo rę mo; mo si ro wipe o to ojo męta nisisiyi ti aşo ti ndi Egun Iwe-irohin "*Eko Akete*" l'owo, ti ko si le jade lati ke "Ho......o" li abę aşo, ki o si fohun bi enia gęgę bi işe rę ni Satide ojo męjomęjo. Ajeje owo kan ko gbe ęru de ori!

Awa mo wipe oran ędun nla ni aijade "*Eko Akete*" ję fun opolopo enia, gęgę bi o ti ję ohun ayo fun awon ti a le pe ni ekute, ti o nfo fęrę kiri ilu nigbati ologini re ajo, ati awon ęlęha obinrin ti o nri aye jade osan gangan nigbati Orò "*Eko Akete*" dękun kike dię lati ojo męta yi wa.

L'oni, ina wo 'le, okunkun p'ara da. Ki eku ile ranşę si ti oko wipe, "*Eko Akete*" de, o si wipe,—Alafia fun gbogbo nyin.

Alafia ni a nfę ni igba gbogbo; alafia ni ile, alafia li oko, alafia ni ibi işę ati alafia ni Ilu: şugbon, iwa ibaje, iwa eke, tęmbęlękun, ireję, panşaga, iwa Olowo şe ohun ti o wu u, ati iwa eri miran gbogbo ha ko ni o nfa ibinu Olorun si Ilu l'ori, ti ko si ję ki alafia po to bi a ti nfę?

Okunrin ko san ju obirin lo, obirin ko duro ni ipo Mammy-oniyeri ti Olorun fi si, agbalagba ko san ju omode lo, igberaga omode ju ti ęiyę Ologese lo; Alufa ko san ju Męmba lo: gbogbo won, iru kanna, obę iwo! Ngbo, ogo ni alafiafia wo Ilu? Alafia ni awa fę, şugbon nigbati a ba soro, ija ni ti won.

### ARUN L'OTA, IKU L'ODI.

Gęgę bi Orilę-ede, ko da mi l'oju wipe Enia Dudu tabi Yoruba apa iha 'hin mo ohun ti o nję Ajakalę-arun ki Oyinbo to de arin wa. Nitoto, Ilę-'gbona tabi Olode (Small Pox) wà ti o nja li ękokan, şugbon ti ko ba si owo araiye tabi awon ti o nsin Şoponna nibę, aisan yi ko nşe oşę pupo ki o to da owo duro.

Influenza tabi arun Ayokęlę, iru eyiti o ja ni odun kefa ohun, arun Oyinbo ni. Anu si şe ni wipe, olori buruku ko nko ran igi tabi opę, enia ni ● ako ori buruku rę ran.

Orişirişi ona ni Oyinbo fi nko arun ran awon enia wa, papa, nipa gbigbe awon odomobirin wa ni ęrękę jo, nitori akętę, bata, ibosę şeda ati aşo ti nwon npe ni Krębişin. Nwon fo awon omobirin wa miran l'ori tobę gę, ti itiju ko si mo fun won lati to Oyinbo lo ni osan gangan; aşo ti Baba tabi Iya ko ni ipa lati da fun omo won, Oyinbo nda a fun won; akętę ati bata ti nwon ko le ra fun won, Oyinbo nra a; awon Obi wonyi nri nkan abami bayi li ara omo won, nwon si dakę: inu won ndun wipe, omo won gbajumo. Boya Iya miran tilę npin ninu Owo ti omo rę ba ri şe li odo Oyinbo; asinwa-asinbo, nigbati omo won ba woji bi oku aro, ti o kun atike titi, ti ko ri ęni pe e mo, nigbana ni nwon to nsare ati ni ika kan, nwon a to Babalawo lo, ki o ba won şe ogun Atidiki, eyiti o nję ki alejo won sa fun won li oşoşu li ailoyun, nigbati nwon ba si ję irora titi li aiye, "Dęręmiti, Wonpapa," bi aşa Rev. Şomuji, o di Orun-alakeji, a-re-ma-bo.

Ni Oko Awo nisisiyi, pi, pi, bi ęni pa ina ni Iku nki omo enia l'orun molę nibę bi adię. Boya, ti a ba si wa idi rę lo siwaju, s'ęhin, o le ję arun Oyinbo ni a o ba nibę; şugbon awon ęlomiran wipe, boya Olorun binu si adugbo na ni, nitori ilękun Moşalaşi Jimo ti Afa Tijani ti nijelo. Eyi le ri bę nitoto, o si le ma ri bę; awamaridi ni işę Olorun. Eyikeyi ti o wu ki o ję, iba şe *Pneumonia*, *Dysentry* tabi arun miran li o nşe oniko-iku ni Oko Awo bayi.

Ęru nba wa, ominu si nko wa gidigidi. Nitorina, a ke si Ijoba, ki o san şokoto giri lati tete koju ija toto-toto si Arun yi, ki o le ti ara awon ara Oko Awo nikanşoşo wa, ki o si ti ara won lo, Arun-alarun ko nran ęşinşin!

### IŞUBU ONIŞOWO.

Owo şişe, (ko nşe owo ęru şişe o) ję işę to dara lopolopo. Ilu ti ko ba si owo ti enia le şe lati so toro di sisi, aboşi ilu ni.

Şaşa ni Oşişę tabi Akowe ti ko fę lati di Onişowo nla ti a o gbo okiki rę kakiri igun męrin Ilu, şugbon gbese ha ko ni gbogbo owo isisiyi nda si enia l'orun?

Bi okunrin ti nşubu, bęri Onigbanjo nko ęru obinrin ta. O kari aiye, Anobi ko gb'owo wa; ko si ki a ta, ki a j'ere, gbogbo aiye di alaigbon, nwon di apa bobo, afonufora.

L'osan, l'oru, ati ni oniruru ona ni awon enia wa nşe ajo ati wahala Owo, nigba pupo ni ewu si nwu won nitori rę; ewu iji lile agbami ti o le s'oju oko de tefetefe, ewu janduku ti o nda ona pęlu ibon ati ada; ewu awon alagbeda, awon, k'a ri, k'a ra, k'a ra, k'a ma san, k'a bere, k'o d'ija: ewu ole ati igara ti o le fo Şabu ji oja ko lo nigbakigba; ewu

Awa ko ro pe ijọ *Ahmadia* ran awọn onisọkuọ wọnyi ni iṣẹ ti nwọn njẹ ọmọ ti nwọn ba si bi bọ ibi iṣẹ na ki nwọn mura lati gbe e pọn—ẹni bi ọrọ ni sa pọn ọ,—toto fun u, owe o!

GBARUKU.

## *Open Letters.*

TO CELEBRITIES, NOTORITIES, ETC., IN DIFFERENT WALKS OF LIFE.

**No. 45.**

To

MRS. C OLAJUMOKE OBASA.
Bafunmi House,
Breadfruit St. Lagos.

Madam,

Without any desire to discuss the merit or demerit of the case which has so unhappily prompted your Open Letter to Mr A. E. Norman-Williams the present Pastor's Warden of your Church (St. Paul's Breadfruit) as published in a recent issue of *The African Messenger* and the Warden's reply in a subsequent number of that paper. I cannot but say that others who have learnt to hold you in high esteem have been sadly disappointed in the *role* of a Meddlesome Matty which you have consciously or unconsciously assumed in that regrettable incident.

I hold no brief for the object of your attack nor am I enamoured of being a sort of Paul Pry in seeing to other people's business, but having regard to your position as a l[illegible] in this country, from whom it is certainly not unreasonable to expect all absence of cant and humbug in matters requiring prudent handling such as the one forming the *fons et origo* of your letter, I am of opinion that it would have been worth your while to let sleeping dogs lie, or devise other less questionable means by which to pour oil on the troubled waters.

Journalistic controversy has its pitfalls no less than its glories.

It is a thousand pities to see that you came out second best in the affray. Better luck next time!

EKO AKETE.

**No. 46.**

To

THE Rt. REV. F. MELVILLE-JONES D.D.
*Bishop of Lagos,*
Bishopscourt,
The Marina, Lagos.

My Lord,

The news came to me recently, like a bolt from the blues that your Lordship has placed your episcopal veto for a twelvemonth hence, on the proposed Ordination into Priest's Orders in the current year, of a young B.A. Curate who is at present, doing duty in one of your leading churches in town, for daring to preach a certain sermon said to be outspoken in its nature, in that church, not long ago: it was also said that this course is resorted to, owing to the crisis through which the head of that particular church is said to be presently passing.

Whilst regretting this *contretemps*, may I be permitted to say that the punishment thus meted out to the young culprit (?): is, to say the least, quite of all proportion to the alleged offence?

Your lordship, I fear, those of different temperament who may chance to hear of this staggering ruling, may be led to think that a scapegoat is being made of the poor, easy-going, and unoffending clergyman.

Would your lordship mind to exercise that Christ-like spirit of forgiveness, and so "be ensample to the flocks"? I pause for a reply.

EKO AKETE.

### "IYAWO DUN LỌṢINGIN ỌKỌ TUN MI GBE."

Ni ijọ Alamisi (*Thursday*) ọsẹ yi ni Oburo wa ọpẹlẹngẹ awẹlẹwa Florence Abẹkẹ Davies di iyawo Cythino Jenkins Kẹhinde Martins—Ni St. Paul *Breadfruit Church* ni a gbe ṣe iyawo na; lẹhinna wọn wa fi a bọ si ile iya Iyawo ni agbo ile Oloye Taiwo Olowo ẹniti o jẹ baba iya iyawo agba (*Granny*)—A ko le rohin onjẹ ati ọti mimu bo ti pọ to—A si dupẹ lọwọ awọn *Uncle* rẹ bi Ephraim Taiwo, Ọgbẹni Augustus Scott ti *John Holt* Babalọla Phillips nwọn ku inawo—Iyawo yi a bi isun, a bi iwarẹ. *Aṣẹ.*

## *STOP PRESS.*

Sir Donald Cameron, K.B.E. Chief Secretary to the Government (Nigeria) appointed Governor of Tangayika.

### ṢỌṢI NLỌ SI'LE ẸJỌ.

A fi akọkọ ro ẹjọ ti *Archdeacon* Ogunbiyi pe Ọgbẹni Thomas H. Jackson, Oni 'we Irohin *Lagos Weekly Record* si ireni (*Tuesday.*)

*Archdeacon* Ogunbiyi gba Ọgbẹni *Lawyer Davies* (Oyinbo.)

Ọgbẹni Jackson si gba awọn Lawyer wọnyi;—Ọlọla J. Egerton Shyngle Ẹbọra ni 'le ẹjọ E. J. Alex. Taiylor, egun-bi-ele ati "Ọmọtaku" Thompson, Ajisọdidun.

## No. 1. LAGOS.

# LEVER STORES LTD.

# OLOWO S'OKE D'ILẸ.

A nta awọn ọja wa ni

**3d. 6d. 9d. 1s**

Oriṣiriṣi ọja wa ni ọpọkuọyọku.

A nti Ilẹkun ni agogo kan ọsọsan Thursday.

A si nti Ilẹkun ni agogo meje alẹ Satide.

## J. C. VAUGHAN

Ti Ile-Ọja Sheffield ni Ita Kakawa ati Ile-Ọja "*Excelsior*" ni Ita Agarawu, ni oniruru awọn ohun kikọle fun tita ni owo ọpọku-ọyọku.

O ti nṣowo Irin Iṣẹ lorişirişi lati adọta ọdun sẹhin titi di oni.

ATARI AJANAKU ni ỌGBẸNI na jẹ ninu awon onişowo Irin Işẹ ni ilu Nigeria.

ỌKỌ tita wa ni owo pọ ọ.



## ILE OWO KADUNA

to mbẹ legbẹ Ile-afin Ọgbẹni A. W. Thomas ni 75 ati 81, Ita Odunfa, (Anikantamọ) L'Eko.

Awa ni orişirişi Kẹkẹ-ologere ati Kẹkẹ pupu-pupu ni tita, a si ni awọn "Ero-ija" wọn pẹlu.

Lati ọdun 1921 l' a ti wa lẹnu işẹ yi, awọn ọja wa si to ọja o ni igba pọun (£200.) Ko si bi Kẹkẹ-ologere kan tabi ti pupu-pupu kan ti le bajẹ to ki a ma gbe'ro: a si nra awọn "cku" Kẹkẹ-ologere, oni-pupu-pupu, ati Ẹrọ-akọrin (*Gramophone*) ti a ntun şe ti a si tun nta lowo pọ̀, bi £3, £4, £6 10 fun awọn ẹniti ko ba to pẹmu olowo-nla ru.

Ẹ wa tabi ẹ kọwe şọwọ si Olotu Ile-owo yi:—Ọgbẹni SAM ADE CLAY ni adugbo ta darukọ loke yi, tabi ni No. 1, Ita Macaulay (Okepopo) l'Eko. Owo lọwọ ni gbogbo Ọja rẹ o, aibamọ.

## ẸWA WO O.

Ọgbẹni E. A. Olemoh ti Ile Işẹ Oluwa ni 73, Ọdunfa Street, (Anikantamọ) berẹ işe agborun titun şe ti baba rẹ nisisiyi. Ojo eşẹ ti iwọ ati Obinrin rẹ ma nsaba ju agborun yin ti o ba bajẹ nu, Kai! Ọgbẹni kan nbẹ ni adugbo mi ti o mọ işẹ agborum nişişe lọpọlọpọ. Pọ lowo rẹ.






*4/6 each.*

## The Kaduna Store,

75 & 81, ODUNFA STREET,
*near Mr. A. W. Thomas's palatial residence.*
ẸBUN HOUSE, LAGOS.

begs to inform all Cyclists and Motorists to *buy* always at our Store, complete spare parts and accessories for all makes of Motors, Bicycles, etc.

Established 1921, we have much pleasure to say that we have added to our STORE, Goods to the tune of £200, being expert in the repairs of Motor-cars, Bicycles and all other machinery. We specialise in the purchase of old Cars, Bicycles, Gramophones which are minutely repaired by us and in turn, sold to those unable to afford high price, at giving-away prices, viz:—£3 £4 £6 10s. respectively, according to durability and taste.

For particulars, apply to the Proprietor:—

SAM ADE: CLAY of the above address, or at 1, Macaulay Street, Lagos.

TERMS:—Cash with Orders.

## What a wonderful Medicine is this?

IS IT MAGIC?

D. A. Thompson, Licensed Herbalist has just received these from Şaki and Barba to cure any complaints brought to him viz:—Ikọ fe e, Warapa Aşiwere, Ọlọ Inu, Pakunpo, Wodi-wodi, Atoriwa Jakutẹ, Oju ti o yọ owo, Jẹdi-jẹdi, with assorted medicines suitable for barren women. Children's treatment and assorted Agunmu in bottles the shop for sale.

*The proof of pudding is in the taste*

**Come and have a trial**

NO. 2, AROLOYA STREET, LAGOS.

# A. Kessler.

7, Labinjo Lane,

Williams Street,

**P.O. Box 459**



THE

# Pilsener Beer

*Lion Brand*

*Light & Sparkling*

**Per Case**

**34s.**

## JACOB AJAYI,

*General Woollen Trader,*

has on hand Woollens in endless variety at 50, Dosunmu Street, Lagos, at

***Prices to suit everybody.***

*Call now, fortune awaits you.*


## *Aworan Alarabara.*

A ni Aworan oniruru fun tita lati fi şe ile ki oşo. A ni ti titę oku Jesu, ti igbati a da a li ębi iku, ti Onję-alę ikęhin. A ni ti Adam ati Efa, ti işędalę aiye, ti Nebuchadenezar nigbati o wa ninu ǫla rę, ati nigbati o di ęranko; ti obirin ti o fi ǫwǫ mu ejo, ati ti Ǫba Tatambulu.

A ni ewe Taba fun kika ta, Oşę Olǫwǫ—agaga; Iyǫ-iyǫ mbę lǫwǫ wa fun tita bi wǫbu, bi o ba fę ę ni *lǫnu* a le ta a fun o, Işana Alapoti fun tita, ko si bi a ti nşe wǫn. Orişirişi ǫja lo wa lǫwǫ wa, iwǫ ko le ba wa şowo ko ma jere tirę, nitori owo pǫku ni a nta wǫn. Owo ǫja wa rǫju rekǫja ala. Bi o ba wa si ile-ǫja wa "Ka mi, ka mi, ka mi" ni gbogbo wǫn, bi o ba fę ja irǫ wa, rin wa si ile ǫja wa.

Iye owo wǫn :—3d, 4d, 5d, 6d, fun ǫkǫkan; 2/6d, 3/-, 4/-, 5/6d fun mejila.

Ibikibi ti o ba ngbe ni *Nigeria* tabi ęhin okun kǫwe şǫwǫ yala ni ede Gęsi tabi ti Yoruba si :—

E. O. AMBĘ & BROS,
38, Moloney Bridge Street, Lagos,
(*Lęgbę awǫn Onişowo A. J. Tangalakis*),
Idumagbo, Eko.

## Ile Ita Egbogi ti Macaulay,

88, BROAD STREET.

Wabiwǫsi orişirişi Egbogi lo şęsę de fun wa ni tita: awǫn bi:—ogun Egbo orişirişi, ogun Ęda, ogun arun aşiri, ogun Aręmǫ, ogun Onigbameji, ogun Aran orişirişi, ogun Lakuregbe, ati awǫn ogun miran ti a ko le mă to lęsęsę.

Ǫpǫku-ǫyǫku ni owo wǫn, nwǫn si ję bi idan.

Ǫrę, ę lǫ dan awǫn Ogun wǫnyi wo nibi ti a gbe nta wǫn.

PRINTED AT "TIKA-TORE" PRINTING WORKS, 20, MARKET STREET, LAGOS, AND PUBLISHED BY ADEOYE DENIGAAT 24, WILLIAMS STREET, LAGOS, WRITER AND LECTURER.